dajudaju ẹjẹ ișan niyẹn, șugbọn maa fi irun silẹ ni odiwọn awọn ọjọ ti o fi maa n ri ẹjẹ nkan oșu, lẹyin naa ki o wa wẹ ki o si kirun

Lati ọdọ Aaisha iya àwọn Mumuni - ki Ọlọhun yọnu si i - dajudaju Faatimah ọmọ Abu Hubaysh bi Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - leere o wa sọ pe: Dajudaju mo jẹ ẹni ti maa n ri ẹjẹ awaada ti mii si ki n si ni imọra, njẹ mo le fi irun silẹ? Ni o wa sọ pe: «Rara, dajudaju ẹjẹ ișan niyẹn, șugbọn maa fi irun silẹ ni odiwọn awọn ọjọ ti o fi maa n ri ẹjẹ nkan oșu, lẹyin naa ki o wa wẹ ki o si kirun».

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Faatimah ọmọ Hubaysh beere lọwọ Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ni o wa sọ pe: Dajudaju ẹjẹ o ki n da lara mi ati pe o si maa n wa titi di igba ti kii șe igba ẹjẹ nkan oșu, njẹ idajọ iyẹn le jẹ idajọ ẹjẹ nkan oșu bii ti maa wa maa gbe irun ju silẹ? Ni Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - wa sọ fun un pe: Dajudaju ẹjẹ awaada ni, oun si ni ẹjẹ aisan kan ti o maa n șẹlẹ lati ipasẹ jija ișan kan nibi apo ibimọ, ati pe kii șe ẹjẹ nkan oșu, Ti asiko ẹjẹ nkan oșu ba de, eyi ti o maa n ri ẹjẹ nkan oșu níbẹ̀ lori ìșesí oșooșu rẹ siwaju ki o to lugbadi aisan ẹjẹ awaada, ki o yaa fi irun ati aawẹ ati nkan ti o yatọ si mejeeji silẹ ni awọn nkan ti wọn kọ fun ẹni ti n ri ẹjẹ nkan oșu kuro nibẹ ni asiko ẹjẹ nkan oșu. Ti odiwọn igba yẹn ba ti wa tan, nigba naa wa jẹ ẹni ti o ti mọra kuro nibi ẹjẹ nkan oșu, ki o yaa fọ aaye ẹjẹ yẹn, lẹyin naa ki o wẹ ara rẹ ni iwẹ ti o pe lati gbe ẹgbin kuro, lẹyin naa ki o wa ki irun.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3029

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee